Abàtà mi, ìrìn oṣù kan ni, omi rẹ funfun ju wàrà lọ, òórùn rẹ dùn ju alumisiki lọ

Lati ọdọ Abdullah ọmọ Amr, ki Olohun yọnu si awọn mejeeji, o sọ pe: Anabi, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a, sọ pe: Abàtà mi, ìrìn oṣù kan ni, omi rẹ funfun ju wàrà lọ, òórùn rẹ dùn ju alumisiki lọ , ife rẹ sì dà bii ìràwọ ojú ọrun, ẹni tí ó bá mu nínú ẹ, òùngbẹ kò nii gbẹ ẹ láéláé.”

[O ni alaafia] [Ohun ti wọn fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun o maa ba a, sọ pe oun yoo ni abàtà kan ni Ọjọ Ajinde, ti òró rẹ yoo jẹ irin oṣu kan, ti ìbú rẹ naa si maa jẹ irin oṣù kan, Omi rẹ funfun ju wara lọ, Oorun rẹ dun ju ti alumisiki lọ, Àwọn àgé omi rẹ pọ bíi ìràwọ ojú ọrun, Ẹnikẹni tí ó bá fi àgé omi náà mu omi ninu abata naa, òùngbẹ kì yóò gbẹ ẹ mọ láéláé.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/65030

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee